## Ẹ GBA IPETU IBOKUN LỌWỌ ADAMALẸṢE

(Lati Ọwọ Z. Akindele Ipetu Ibokun)

siỌrọ yi jẹ ẹdun ọkan mi, mo nfẹ alaye le lori ọrọ na ni wipe, ipo wo ni Ile-iwe wa ni akoko yi, nitori pupọ nkan ni tori pupọ nkan ni mo nri to ru mi loju lori ọrọ Ile iwe papa ti Ipetu-Ibokun.

Ṣaju kia to bẹrẹ Ile-iwe ni ọdun yi ni olubẹwo Ile iwe Ipetu sọ fun awọn ara Ipetu wipe on yio funwọn ni iwe mẹfa lọdun (Primary Six) o si mu ileri rẹ ṣẹ gẹgẹbi ohun ti o wi

Ṣugbọn ẹhn ti wọn ti bẹrẹ si ka iwe na (Primary Six) ni o tun kọwe pe ọga Ile-iwe gbogbogbo (Ebucatoin Officer ko tun fi ara mọ a ti ma ka iwe mẹfa mọ (Primary Six). Ninu iwe ti o kọ si Ọga ile-ile ipetu: Awọn Ọgbẹni Ilọri ati Ajetunmọbi wipe, Educatiou Offiœr tikọ lati fọwọsi a ti ma ka iwe mẹfa ni (Primary Six) Ipetu-Ibokun ati wipe awọn ọmọ to nko iwe mẹfa na ki awọn tu wọn ka, ki wọn si bẹrẹ ile iwe ni Ọtan-Ile lọla ati papa on ko le ran awa Ipetu- bokun lọwọ mọ nitoripe ara Ipetu-Ibokun sọpe on ko owo jẹ.

Lẹhin eyi ni Apetu Salaro, Lasisi Ade Bello, Mich Ojo, Ọgbẹni Pa Falokun lọ si ọdọ Olubẹwo wọn bẹ titi ṣugbọu ko fuu wọn laye lati ma ka iwe mẹfa na ni ẹ. Nitori idi eyi, inu mi yio dun ti mo ba le gbọ alaye kiakia lori ọrọ wọnyi.

Ekini Njẹ otitọ ni Alaṣẹ Ile Iwe kọ lati fọwọ si kika iwe mẹfa (Primary Six) ni Ipetu-Ibokun ni 1956? (b) B o ba jẹ otitọ Njẹ otitọ bẹni gẹgẹbi alaṣẹ Ile-iwe ati ẹniti o mọ pupọ nipa Ile-Iwe na ni ẹtọ lati da fi aye iwe kika iwe mẹfa silẹ laiti gba iyọnda lọdọ Ijọba Eduction Offier

Njẹ o ṣe bẹ nipa ti Ipetu Ibokun?

Bio bajẹ wipe ogba iwe iyọnda lọdọ Ijọba (Letter of Aproval) ki wọn to bẹrẹ si ka iwe na.

(d) Kini idi re ti ijọba fi ṣe lodi si ipinu wọn lori kika Iwe mẹfa ni Ipetu Ibokun?

(e) Bi ijọba ko bati yọnda fun kini ẹtọ rọ lati da iwe mẹfa silẹ ni Ipetu-Ibokun nigbti o mọ daju pe laigba iyọnda lọdọ Ijọba nigbeti ko ni ẹtọ lati ka iwe mẹfa ni Ipetu-Ibokun?

(f) Inu ipo wo lo fẹ ki awọn ọmọ na wa, nigbati o jẹ wipe ara Ipetu-Ibokun ko bere fun iwe mẹfa (Primary Six) lọdun yi, ki a to ṣe ileri rẹ fun wọn?

(g) Njẹ o ha ṣeṣe ki awọn ọmọ ilẹ yi ti wọn wa ni iwe kẹfa primary Six fẹsun kan pe o da ọna wọn ru nitoripe wọn nlọ si ile iwe kan ri ni ilu bi Ọtan ati Ibokun ati wipe on lo sọpe ki wọn wa ma ka iwe wọn ni Ipetu-Ibokun lajẹpe wọn sọpe inira wa fun wọn nibiti wọn nlọ tẹleri?

(h) Nitori awọn idi pataki wọnyi iba dara ki ijọba Ijẹṣa (Ijesha-Divisional Council) gba ile iwe Ipetu Iboku si ọwọ ara wọn yatọ si wipe ki ẹnikan ma dawa ribaribo nitori a si gbọ wipe eto ile iwe ti wa lọwọ Ijọba. (Western-Regional Govement)

Nipa idi wọnyi, Ile-iwe ti o wa ni Ipetu Ibokun gbogbo ilu lo kọ ati wipe lẹhin kikọ rẹ awọn to nṣe to ohun ti oba su ijọ nibẹ niwọnyi, Ijọ methodist ni Awọn Imale (moslem) ati ijọ Aposteli (aladura)

Nigbati o jẹ wipe awọn olusin mẹfa yi lo nṣeto ile iwe na njẹ ko ha pọ si ọnakan wipe olubẹwo Ijọ Methodist lo nṣe akoso rẹ.

Kini ti awọn Imale ati ti Aposteli (Aladura) tijẹ,

Nitori idi eyi mo bẹ Ijọba Ijẹṣa (Ijesha Divisional Council) ki wọn gba ile-iwe na si ọwọ ara wọn nitoripe Ijọ Methodist, awọn Imale ati Apesteli abẹ ijọba Ijeẹṣa kanna ni awọn mẹtẹta wa.

Mo kọ iwe yi gẹgẹ bi ọmọ ati bi tabi ara Ipetu ati ẹniti o nsan owo ori silẹ kiṣe gẹgẹbi Kansẹlọ I wrote this article as a citizen (and Tax payer but not as Councillor)

Koiti pari kẹ ma reti mi ni ọsẹ to mbọ nigbana ni eo gbọ kulagbe ọrọ lori ile iwe ti mbẹ ni Ipetu Ibokun.

Mo dupẹ Olotu Irawọ Obokun fun aye to gbami fun gbolohun meji yi.

---



ỌGBẸNI J. O. LAYIDE

Nipa Ọgbẹni wa ... ni iwe kan to wa lati Erinmọ jade ninu oṣu October 1954. Lẹhin iwadi Olotu gba pe ọrọ on jina si otitọ nitorina oti tọrọ aforiji lọdọ Ọgbẹni I. O. Layide.

---

## KANSELỌ TITUN MẸRIN FUN ILẸṢA:

Lẹhin igbati wọn ṣe idibo yan Kansẹlọ sinu awọn igbimọ ijọba Ilẹṣa ni ipo mẹrin ṣi silẹ ninu awọn kanselọ ti igboro Ilesa.

Awọn Adugbo mẹrin na ni Ayesọ, Orikiran. Isọna ati Ijọkat Ni ọjọ kẹsan osu to nbọ (March) ni ọjọ idibo si awọn ipo mẹrẹrin to ṣofo na.

Awọn wọnyi ni a gbọ pe o ti foruko silẹ loruko Ẹgbẹ Al kuko: David Ajayi fun Ijọka; Yesufu Saani fun Ayesọ; Francis Oguntominiyi fun Isọna; Joseph Lawrence Alake fun Ọrikiran.



ALAIYELUWA AJIMỌKỌ KEJI ỌWA ILẸṢA.

Lati fun ṣiṣẹ ajọdun ọdun iwude irọrun igbimọ faramọ imọran aba Kansẹlọ Akindele Ojo Famọto pe ki ọjọ iwude jẹ ọjọ iyasọtọ gẹgẹbi ọjọ ajọdun Ijẹṣa ati pe ki ijọba dari awọn motọ to le ṣe idiwọ iṣajọdun na si adugbo miran ki alafia le wa fun awọn nṣọdun na.

---

## IRIN-AJO AWOLỌWỌ NIPA IDASILẸ IṢẸ.

Ikede jade lati ikorita iṣẹ ijọba Ẹkun Iwọ Orun Nigeria lọsẹ to kọja pe Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ, ẹniti o jẹ olori awọn oluṣe o ijọba Ẹkun yi yio ṣe aṣaju awọn ti yio rin irin ajo nipa idasilẹ iṣẹ lọ si ilu oyinbo.

Iru irin ajo bẹ ni awọn Ọlọla Nnamdi Aṣikiwe ati L. P. Ojukwu rin lọ silu oyinbo ninu ọdun 1954 ti wọn yio de ọpọlọpọ ilu. Ọlọla Awolọwọ sọ pe ko boju mu. O ni yatọ fun ipokiki, iṣẹ agbẹ lo yẹ ki ijọba to ba meto gbajumọ.

Ọrọ Ọlọla na lori irin-ajo idasilẹ jade ninu "Daily Times" ti ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu May 1954.

Ni ọjọ kejila oṣu March ni wọn nlọ, wọn yio pada larin oṣu April. A gbọ pe

---

## ILESHA COMMUNITY CENTRE

### ADVISORY BOARD COMMITTEE

**There will be an emergency meeting of the above named Committee at the Centre (old Post Office) on Monday, 27th February. 1956 at 5: 30 p.m.**

**Agenda:—**

1. Minutes & Matters arising
2. Finance
3. Boxing Ring
4. General.

HON. SECRETARY,

